# ÌWÀ ỌMỌLÚÀBÍ NÍNÚ EWÌ *EWÌ ÌGBÀ LONÍGBÀ Á KÀ* TÍ OLÚYẸ́MISÍ ADÉBỌ̀WÁLÉ KỌ

## LÁTI ỌWỌ́

**TÁYÉ FATIMA SHEU**

**DEPARTMENT OF NIGERIAN LANGUAGES**

**Àṣamọ̀**

*Ìwà ìbàjẹ́ tí ó wà ní àwùjọ ní ilẹ̀ kááàrọ̀-oò-jíire jẹ́ ohun tí ó ba ènìyàn nínú jẹ́. Àwọn ìwà burúkú ló gbòde kan ní àwùjọ wa báyìí. Ìwà Ọmọlúàbí ti di ohun àfiṣẹ́yìn tí eégún ń fi fiṣọ. Nínú bébà yìí, a ó sọ ohun tí ìwà ọmọlúàbí jẹ́, a sì tẹ̀ síwájú láti ṣàlàyé lórí àwọn kókó márùn-ún tí a pín ìwà ọmọlúàbí sí nínú* *Ewì Ìgbàlonígbà á kà* tí Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé kọ.

**Ìfáàrà**

Kò sí òǹkọ̀wé kan tí yóò kọ̀wé láìjẹ́ pé ó ní èròǹgbà kan lọ́kàn tó fẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀. Èrò òǹkọ̀wé nígbà mìíràn lè jẹ́ nípa ọ̀rọ̀ òṣèlú, ẹ̀sìn tàbí ọ̀rọ̀ ajé àwùjọ kan, kódà òǹkọ̀wé tún lè fi ìwé rẹ̀ bu ẹnu àtẹ́ lu nǹkan ó sì tún le fi gbé e lárugẹ. Ṣùgbọ́n ohun tó kojú ṣẹ́nìkan, ẹ̀yìn ló kọ sí ẹlòmíràn èyí ló fà á tí a fi lè rí kí òǹkọ̀wé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ má a sọ̀rọ̀, nípa nǹkan kan náà tó jẹ́ wí pé ìhà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni oníkálukú wọn kọ sí nǹkan náà.

Nínú *Ìwé Ìgbà lonígbà á kà,* ohun tí òǹkọ̀wé fẹnu rẹ̀ jóná lé lórí ni Ìwà Ọmọlúàbí, láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni ìran Yorùbá ti káràmáásìkí kíkọ́ ọmọ ní ẹ̀kọ́, ìwà ọmọlúàbí. Lóòótọ́ kò sí ìwé kan tí á kà tí kò níkọ́ni ní ẹ̀kọ́, pàápàá jùlọ ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí tó jẹ́ ìran Yorùbá lógún ṣùgbọ́n tinú ìwé yìí kọyọyọ nítorí gbogbo ẹ̀kọ́ ayé ló mẹ́nu bà tó yẹ kí á bá lọ́wọ́ ọmọlúàbí ènìyàn ló kún inú ewì náà.

Nínú àpilẹ̀kọ mi yìí, á wo ohun tí Ewì jẹ́, àti inú àwọn ewì tó ti mẹ́nuba ìwà ọmọlúàbí. Àwọn ewì náà ni "Bọ́mọdé Láṣọ bí Àgbà", "Wòsọ̀ Dèmí", "A-jí-gbọ́-toge", "Atẹ́ẹ́rẹ́-Loge", "Wọn ń wò yín",. "Farabalẹ̀ Gbade".

**Tíọ́rì**

Tíọ́rì soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni a ṣe àmúlò rẹ̀ nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí. Onímọ̀ ìjìnlẹ̀ Faransé tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Taine ló ṣe agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí. Tíọ́rì yìí dálé ohun tí ó jẹ mọ́ ìbágbépọ̀ àwùjọ, ìbáṣepọ̀ tó wà

láàárín àwùjọ ọmọ ènìyàn àti ìràpadà lọ́wọ́ ìbàjẹ́ àwùjọ. Ohun tí ó ń lọ nínú àwùjọ ló jẹ tíọ́rì yìí lógún. Tí ó bá rí bẹ́ẹ̀, a kò sìnà tí a bá lo tíọ́rì Sọ̀síọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ láti fi wo àwọn ìwà ọmọlúàbí tí ó súyọ nínú ìwé _*Ewì Ìgbàlonígbà á kà,*_ níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ wí pé inú àwùjọ ni òǹkọ̀wé náà ti wá, kò sì gbọdọ̀ rí ohun tó ń lọ nínú àwùjọ tì, yálà ìwà ìbàjẹ́ tàbí ìwà ọmọlúàbí.

**Ta ni Ọmọlúàbí?**

Abímbọ́lá (1971:34) sọ pé:

> Ọmọlúàbí ni ènìyàn tó ní àwọn àbùdá ìwà rere bíi sùúrù, ìfanimọ́ra, ìtẹríba, ọ̀yàyà, lílòdì sí àgbèrè àti panṣágà, ojú kòkòrò, olè, òfófó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Láti ọjọ́ pípẹ́ ni Yorùbá ti ní ọ̀nà tàbí ètò tí wọ́n ń gbà fi kọ́ ọmọ láwùjọ wọn, kí ó tó di pé ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ, mọ̀-ọ́n-kà dé inú àwùjọ wa, ni àwọn Yorùbá ti ní ìlànà tí wọ́n ń gbà ṣe èyí nínú àwùjọ wa. Èyí ni Awóníyì (1978:25) rí, tí ó fi sọ pé:

> Èròǹgbà àwọn Yorùbá nípa ẹ̀kọ́ ni láti jẹ́ ọmọlúàbí. Èyí náà ló sì jẹ́ àtubọ̀tán kíkọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ wọn, mímú ẹnìkọ̀ọ̀kan ya ọmọlúàbí láwùjọ. Láti jẹ́ ọmọlúàbí yìí ni láti ní ìwà rere, kí á sì jẹ́ ẹni ìtẹ̀wọ́gbà ní gbogbo ọ̀nà.

Ọmọlúàbí tí Awóníyì (1978) ń tọ́ka sí ni, ẹni tó kó gbogbo ìwà rere pọ̀, tó sì jẹ́ ẹni tí ẹlẹgbẹ́ àti ojúgbà kà sí ojúlówó ènìyàn. Ẹni tó jẹ́ olóòótọ́ àti olódodo ènìyàn, tó tẹpá mọ́ṣẹ́ tí kò rojú, tó ní ìforítì, tó sì ṣe é fọkàn tán láwùjọ rẹ̀. Bí ènìyàn bá ní ìwà tó lòdì sí èyí, kì í ṣe ọmọlúàbí ẹ̀dá, irú ẹni bẹ́ẹ̀ sì ni a lè gbà pé kò ní ẹ̀kọ́ ilé. Adójútini ní àwùjọ ni Yorùbá ka irú àwọn bẹ́ẹ̀ sí pẹ̀lú. Àyípadà tó dé bá ìwà ọmọlúàbí ní àwùjọ wa, ló gun akéwì yìí (Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé) ní kẹ́sẹ́ inú, tó fi kọ́ àwọn ewì rẹ̀ kọ̀ọ̀kan lá ti fi pé wà padà sí ojú ọ̀nà ìwà ọmọlúàbí. Kókó márùn-ún ni a pín ìwà ọmọlúàbí sí nínú _*Ewì Ìgbàlonígbà á kà*_ tí á ṣe àlàyé lórí wọn.

**Ewì**

Ewì lápapọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà mẹ́ta tí lítíréṣọ̀ pín sí. Tí a bá mú ewì, ẹ̀yà méjì tó kù ni eré onítàn àti eré-oníṣe àti ìtàn àròsọ. Nínú ẹ̀ka lítíréṣọ̀ mẹ́tẹ̀ẹta yìí, ewì ló má a ń ṣàmúlò èdè lọ́nà tó

wuyì jùlọ. Èyí ló mú kí Akínjógbìn (1969) náà jẹ́rìí sí i pé ìlò èdè ló ya ewì sọ́tọ̀ sí ọ̀rọ̀ wuuru, ó sọ báyìí pé:

> Nínú gbogbo èdè pátápátá ẹ̀wà ewì má a ń pọ̀ju ti ọ̀rọ̀ wuuru lásán lọ.

Ọ̀pádọ̀tun (1982:11) kí ewì báyìí pé:

> Ewì jẹ́ àkójọpọ̀ àsàyàn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí a má a ń fi ohun dídùn ké lọ́pọ̀ ìgbà, tí ó sì má a ń ní ìgbóhùn sókè sódò ní òpin gbólóhùn àti lórí ẹyọ ọ̀rọ̀ pàtàkì, bákan náà sì ni onírúurú ọnà èdè má a ń táwọ́ tásẹ̀ nínú rẹ̀.

Bí a bá wo oríkì tí Ọ̀pádọ̀tun fún ewì, a ó rí i pé èdè ní akéwì má a ń lò, ṣùgbọ́n ọ̀nà tí akéwì tàbí a-kọ-ewì má a ń gbà lo èdè má a ń yàtọ̀ sí ti ẹ̀ka lítíréṣọ̀ yòókù.

**Àgbéyẹ̀wò Ìtúpalẹ̀ àwọn Ewì tó dálé ìwà Ọmọlúàbí**

Àkọ́kọ́ nínú márùn-ún tí a le pín ìwà ọmọlúàbí tí òǹkọ̀wé ń tẹnumọ́ nínú àwọn ewì inú *Ewì Ìgbàloníìgbà á kà* ni a lè pè ní *Gbígba Ìmọ̀ràn Àgbà*. A rí èyí nínú ewì tó pè ní *Bọ́mọdé Láṣọ bí Àgbà*. Nǹkan tó ń sọ fún wa nínú ewì náà ni pé kí á má fojú di ìmọ̀ràn àgbà àti pé kí á yé jẹ́ kí ọ̀làjú òde òní bá àṣà waje. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mo pé ìran Yorùbá fẹ́ràn àti má a ka ọ̀rọ̀ àgbà sí nítorí pé wọ́n gbà pé ẹnu àgbà lobì ń gbó àti pé ìrírí ní í mágbà gbọ́n. Ọ̀nà tí ó gbà lo èdè nínú ewì *Bọ́mọdé Láṣọ bí Àgbà* la fi mọ̀ pé òǹkọ̀wé kò faramọ́ ìwà ọ̀làjú tí àwọn ọ̀dọ́ ìwòyí ń hù tí wọn kò fi ka ìmọ̀ràn àgbà kún.

> Àìmọ̀kan ọ̀dọ́ ní í mú wọn í ṣẹṣẹ̀ gbé
>
> Àìlóyetó ìpẹ́ẹ̀rẹ̀ ní í mú wọn í sìwà hù
>
> Ẹ̀yin ò mọ̀ pé ìrírí ní í mágbà gbọ́n
>
> Tọ́gbọ́n fi fàtàrí àgbà ṣebùdó
>
> Tágbà kì í fi í wà lọ́jà

Kórí ọmọ titun ó wọ́ lójú u wọn.

Ohun mìíràn tí òǹkọ̀wé tún fẹ́ kí a mọ̀ nínú *Ewì Ìgbàlonígbà á kà* ni jíjẹ́ olóòótọ́. A rí èyí nínú ewì tó pe àkọlé rẹ̀ ní Wòṣọ́ Dèmí. A rí i pé ẹni a pè wá jẹun tó tún múni lọ́wọ́ dání, ó sì fi àdàbà ṣe ẹni tí a pè wá tó ń gbèrò aburú sí ọ̀kín. Nípa bí òǹkọ̀wé ṣe lo èdè ni a ṣe mọ̀ pé ó ń gbìyànjú àti sọ àtunbọ̀tán ẹni tí kò bá jẹ́ olóòótọ́ fún wa.

Ọ̀kín doríkodò ó ń wòṣe Àdàbà

Bẹ́ẹ̀ ló ń pète pèrò

Láti gbàsọ̀ lọ́wọ́ onísọ̀

Èrò bó le wó kó wó ní í pa

Èrò bó le bàjẹ́ kó bàjẹ́ ní í gbà ...

Àmọ̀ bó ti léri léka tó

Pàbó níyànjú rẹ̀ ń já sí

Ẹ wẹni a pè wá jẹun tó fẹ́ gbàjẹ

Lẹ́nu olóúnjẹ

Ẹ wẹni a pè wá sojú ẹni t'ó fẹ́

Yọni lójú sọnú

Akéwì jẹ́ kí á mọ̀ pé Ọlọ́run nìkan ló le gbani lọ́wọ́ ẹni tí a fẹ́ tí kò fọkàn fẹ́ni.

Orí ni kó gbani lọ́wọ́ aṣebi

Elédùà ni kó gbani lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ ọ̀dàlẹ̀.

Kókó mìíràn tí a tún rí fàyọ nínú *Ewì Ìgbàlonígbà á kà* ni Ìwà Àgbèrè. A rí èyí nínú ewì tó pè ní *A-jí-gbọ́-toge*. Nínú ewì náà a rí i pé bí àwùjọ ṣe rí lóde òní ni òǹkọ̀wé fihàn. Ó sọ̀rọ̀ nípa ọkùnrin àti obìnrin tó jẹ́ pé wọ́n tìtorí àgbèrè fẹ́ bayé ara wọn jẹ́.

Ajígbọ́toge àdúgbò

Bó gbé dúdú

A tún gbé pupa

A sì gbé wèrè ṣàgbésùn dánwò

Ajígbọ́toge á tún lẹ̀dí mábo tí ò mọ̀ rí

Láì náání éèdì tí ń bẹ lóde.

Ohun tí òǹkọ̀wé fẹ́ ká mọ̀ nínú ewì Ajígbọ́toge ni pé àwọn ọkùnrin òde òní ń tìtorí nǹkan tí wọ́n má á jẹ wọ́n fẹ́ fi bara wọn láyé jẹ́. Ní ìparí ewì náà ni òǹkọ̀wé wá jẹ́ kí á mọ ìhà tí ó kọ sí irú ìwà yìí àti pé ó tún jẹ́ kí á mọ àtubọ̀tán irú ìwà yìí.

Àmọ́ ohun tó dùn a má a pani

Àní ohun tó dùn a má a tini sí kòtò

Ohun tó dùn a má a pànìyàn.

Ewì mìíràn tó tún dàbí rẹ̀ ni ewì tó pè ní *Atẹ̀ẹrẹ́-loge*. Nínú ewì náà, òǹkọ̀wé ṣe àfihàn irú ìgbé-ayé tí àwọn obìnrin òde òní ń gbé pàápàá jùlọ ìmúra wọn tó jẹ́ pé nítorí ọkùnrin náà ni wọ́n ṣe ń rin ìhòhò kiri.

Ikún ń jọ̀gẹ̀dẹ̀, ikún ń rèdí

Ikún gbàgbé póhun tó dùn ní ń pani ...

Ẹ yé fìhòhò yín dàlú rú

Ẹ yé fìdí yín dagbo rú

Ẹ yé fara yín bayé jẹ́

Ẹ̀yin sisí, ẹ rántí ọjọ́ alẹ́

Ọ̀làjú ò pé ẹ má mẹ̀tọ́

Éèdì ń bẹ lóde ...

Ẹ rántí, póhun tó dùn ń pani

Àní, ẹ rántí, póhun tó dùn ń pànìyàn

Kókó mìíràn tí a tún rí fàyọ nínú *Ewì Ìgbà lonígbà á kà* ni pàtàkì *Ẹ̀kọ́ Ilé,* gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé ìran Yorùbá káràmáásìkí kíkọ́ ọmọ ní ẹ̀kọ́ ilé. Ó le jẹ́ nípa ìwà wọn ni èyí tí wọ́n mọ̀ pé ó má a ń nípa lórí ọmọ tàbí kí wọ́n má a kọ́ ọmọ ní onírúurú nǹkan tí ó jẹ́ ti ọmọlúàbí láti kékeré.

Òǹkọ̀wé jẹ́ kí á mọ̀ pé ọ̀làjú tó gbòde kan báyìí ti mú àyípadà bá ìgbé ayé ọmọnìyàn lọ́pọ̀lọpọ̀, bí àpẹẹrẹ ìgbé ayé lọ́kọ-láyà ti yàtọ̀ sí ti àtijọ́, fífi ẹ̀kọ́ ilé kọ́ ọmọ kò jẹ ọ̀pọ̀lọpọ̀ òbí lógún mọ́. Èyí jẹ́ ohun tí òǹkọ̀wé ń sọ nínú ewì tó pè ní *Wọ́n Ń Wò Yín*. Nínú ewì náà òǹkọ̀wé jẹ́ kí á mọ̀ pé ó yẹ kí àwọn òbí má a hu ìwà tí yóò mú kí àwọn ọmọ wọn jẹ́ ènìyàn lọ́jọ́ iwájú. Pàtàkì nǹkan tí òǹkọ̀wé fẹ́ ká mọ̀ nínú ewì náà ni pé irú ìgbé ayé tí àwọn òbí bá gbé má a ń nípa lórí àwọn ọmọ. Òǹkọ̀wé gba àwọn òbí níyànjú pé kí wọ́n má si àwọn ọmọ wọn lọ́nà pẹ̀lú àwọn ìwà burúkú tí wọ́n ń hù.

... Ẹ̀yin ti gbàgbé ọ̀rọ̀ àgbà tóni

Ẹsin iwájú ni ti ẹ̀yìn ń wò sáré

Ọmọ tí òbí ò ṣe ohun kan gúnmọ́ lójú ẹ̀

Á a ṣe é retí kí irú rẹ̀ ó ya ọmọlúàbí? ...

Ìwọ bàbá tó o le mú ìtọ̀

Rántí òwe tí ò ń fí pa fún ọmọ

Ìwọ ìyá tí ò ń fọtí wẹ̀ bí òjò

Rántí àrokò tí ò ń fèyí pa fún ọmọ.

Lẹ́yìn tí òǹkọ̀wé ti sọ̀rọ̀ nípa irú ìwà tí kò dára tí kò sì yẹ kí àwọn òbí má a hù ni ó wá gbà wọ́n ní ìmọ̀ràn pé kí wọ́n jáwọ́ nítorí ọjọ́ ọ̀la.

Bí ìwà rẹ bá sọ ọmọ rẹ di ìdàkaudà

Fi ojú inú wo bí ọjọ́ ọ̀la ọmọ rẹ̀ yóò ṣe rí

Ó bá má ba ọjọ́ ọ̀la ọmọ rẹ̀ jẹ́

Pa ìwà dà kó o tún ìwà rẹ hù

Máṣe má a pe ìgbẹ́ lọ́nà fún ògo ọ̀la.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé síwájú pé ọ̀nà márùn-ún ni a pín ìwà ọmọlúàbí tó jẹ́ kókó nǹkan tí òǹkọ̀wé fẹ́ kí á mọ̀ nínú *Ewì Ìgbàlonígbà á kà* sí, nǹkan karùn-ún tí a rí fàyọ ni sùúrù. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé sùúrù jẹ́ nǹkan tí Yorùbá fẹ́ràn láti má a fi kọ́ àwọn ọmọ wọn. Ìran Yorùbá gbàgbọ́ pé sùúrù le ṣe òkúta jinná ìdí nìyí tí wọ́n fi má a ń gbìyànjú láti má a mú sùúrù ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn. Nínú ewì tó pè ní *Farabalẹ̀ Gbadé*, òǹkọ̀wé ń gba àwọn obìnrin níyànjú pé kí wọ́n má sáré ní ọkọ nítorí ilé ọkọ kì í ṣe àkánjúlọ rárá àti pé onírúurú ọkùnrin ló ń bẹ lóde tó sì ṣe pé díẹ̀ lára wọn lèèyàn le fi ṣọkọ nínú wọn. Akéwì ní:

Sùúrù lọ̀rọ̀ ọ̀hun gbà

Ṣe onísùúrù ní kúkú fún wàrà Kìnnìún

Bá a fi wádúwádú jẹun, ata á sá pá ni lórí

Bá a farabalẹ̀ jẹun, ọkàn á sí balẹ̀ wọ̀ọ̀

Èmi ló dé tá à fi í kánjú?

Èmi ló dé tá à fi farabalẹ̀?

Ṣe torí adé a fẹ́ gbà yìí náà ni?

Ọ̀rẹ́ rántí pé apẹ́jẹun kì í jẹ̀bàjẹ́.

Ní àkótán, a le sọ pé ohun tó jẹ́ òǹkọ̀wé lógún ni ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí. Òǹkọ̀wé náà fi àwọn ewì rẹ̀ wọ̀nyí ṣe àlàyé wí pé àìsí ìwà ọmọlúàbí ló bá àwùjọ wa débi tí a wà lónìí yìí, èyí sì ń fẹ́ àtúnṣe bí a bá fẹ́ kí àwùjọ wa tẹ̀síwájú.

Ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí ṣe pàtàkì nínú ìgbésí ayé ọmọnìyàn. Àwọn Yorùbá mọ pàtàkì ìwà ọmọlúàbí, ni wọ́n fi máa ń pa ọwọ́ pọ̀ kọ́ ọmọ wọn ní agbo ilé láàárín àwọn mọ̀lẹ́bí. Wọ́n ti mọ̀ pé, bí ọmọ bá sìwà hù ní àwùjọ, gbogbo ẹbí àti ará ni aráyé yóò máa sọ òkò èèbù sí. Torí náà ìwà rere ni ẹ̀ṣọ́ ènìyàn, ká fi ìwà ọmọlúàbí kọ́ àwọn ọmọ wa.

**ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ**

Abímbọ́lá, W. (1971). *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀ríndínlógún.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adébọ̀wálé, O. (2000). *Ewì Ìgbà lonígbà á kà.* Capstone Publishers.

Akínjógbìn, A. (1969). *Ewì Ìwòyí*. Scotland: Collins Sons and Co. U.K.

Awóníyì, T.A. (1978). *Yorùbá Language in Education.* Ìbàdàn: Oxford University Press.